ILE-IFE

## AWỌN ALATAKO BINU JADE NI IGBIMỌ

Nigbati Igbimọ Ijọba Ile-Ifẹ (Ife District Council) pade ni gbongan Afin Ife ni ọjọ kẹrinla oşu yi, ijoye mẹtaleiogun, awọn ọmọ Ẹgbẹ Action Group Elerin mẹsan, ọmọ ẹgbẹ NCNC mẹwa ati ọmọ Ẹgbẹ Adunni Oluwọle mẹta lo binu jade kuro ninu ipade na nigbati igbimọ yi kọ aba ti Kansẹlọ Orafidiya (AG Elerin) mu wa wipe ki a sun ọjọ ti wọn yio yan komiti siwaju diẹ si ki ede aiyede ti o wa ni igbimọ na le fi ka ẹẹ silẹ.

Kansẹlọ na fi ye igbimọ wipe ti nwọn ba yan komiti laironu si ọrọ ti nwọn sọ, yio jẹki enia funra si wọn wipe o ni nkan kọlọfin ti nwọn fẹ fi yiyan komiti pajawiri na şe.

Nigbati Kansẹlọ Adeleke (AG Talaka Parapọ) daba wipe ki a yan ti ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ rẹ farambọ ni gbogbo awọn alatako igbimọ na binu jade.

Onirohin wa fi ye wa wipe igba keji ti awọn alatako yio binu jade larin oşu yi niyẹn. Nwọn kọkọ binu jade nigbati Alaga Igbimọ na Ọgbẹni Fani Kayọde kọ fun ọkan ninu Oloye ni aye lati dibo yiyan alaga. Ọgbẹni Fani Kayọde şe alaye wipe ko i ti pẹ ti won fi Aguro joye. Ẹgbẹ alatako ko fi ara mọ alaye yi nwọn si binu jade.

A tilẹ gbọ wipe Ajẹle (D. O.), Ọgbẹni Brett fun igbimọ ni imọran wipe ki nwọn maşe yan alaga ni ọjọ keje oşu yi şugbọn igbimọ ko fara mọ imọran na.

Ni ọjọ kẹrinla oşu yi, bi nwọn ti gbadura tan ni Ajẹle, Ọgbẹni Brett wipe o şe on ni anu lati sọ fun igbimọ na wipe on ti şetan lati lọ fun isimi diẹ ni ile oyinbo. O si fi ẹniti yio rọpo on, Ọgbẹni Fyffo, han igbimọ na. O gba igbimọ ni imọran lati şişẹ ribiribi bi ti o wa ni iwaju nwọn pẹlu sowọpọ awọn alatako.

Ọgbẹni Fani Kayọde (-laga) sọ wipe on f'awọn kansẹlọ aye lati sọrọ si akan ti Ajẹlẹ na wi nitori pe on ko i ti ba Ọgbẹni na şişẹ ri.

Kansẹlọ S. O. Ogunyẹmi (NCNC) fesi si ọrọ na gẹgẹ bi olori gbẹ Alatako igbimọ na. O dupẹ lọwọ Ajẹlẹ na fun işẹ ribiribi ti o şe ni Ifẹ. O bẹ Ọlọrun ki o sọ alọ ati abọ rẹ. Kansẹlọ Ayo Martins na sọrọ rere nipa Ajẹlẹ na.

Nigbati akọwe igbimọ na ka akọsilẹ nkan ti o şẹlẹ ni ipade akọkọ, Olori Alatako, kansẹlọ S. O. Ogunyẹmi (NCNC) fi han ipade wipe akọsilẹ na ko pe.

A gbọ wipe igbimọ yan komiti ki nwọn to pari ipade na. Onirohin "Irawọ Obokun" fi ye wa wipe ipade Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ile-Ifẹ yio wa ni ọjọ kejilelogun oşu yi.

Oluşeto ijọba Ẹkun Iwọ Orun Naijiria, Ọgbẹni Rotimi Williams yio ba igbimọ na sọrọ, wọn yio si yan alaga igbimọ ni ọjọ na.

## KOTU IBILẸ IWO NFẸ ABOJUTO

(Lati Ọwọ Ọlajide Owoeyọ, Iwo.)

Lati ọjọ ti mo ti nrin ile aiye, ti mo si nri gẹgẹ bi awọn adajọ ti nşe ni Kotu gbogbo, ti awọn kan ni akaọm Iwo şẹru bami fun idakuda ẹjọ ti wọn ma da, ti wọn fi ojuşaju ngbe ẹbi funalare tabfun ẹlẹbi. Emi ko rope Ọlọrun fẹ bẹ rara.

Eyiyi fi han daju pe iru enia bẹ ko tọ lati fişe onidajọ, atipe awọn wọnyi ko tẹle ofin kankan lati fi dajọ ninu Kotu, atipe aimọkan, ati aimoye wọn papa nyọ wọn lenu.

Ki ẹlejọ meji to ro tẹnu wọn tan, wọn ti sun lọ lori ijoko wọn. Njẹ bawo ni irufẹ enia bayi tişe le mọ irufẹ idajọ ti yio şe? Nigbati o jẹ pe adajọ su lọ nigbati wọn fi nro ẹjọ niwaju rẹ: Bawo ni wọn şe mọ ohun ti wọn yio da lejọ? Şugbọn nigbati wọn ba taji lojiji idajọ to ti wa lọkan wọn lati ile wa ni wọn yio şe. Nwọn ki i tẹle ilana ofin ti ijọba fi silẹ fun wọn.

Irufẹ iwa bayi ko dara o fi aye silẹ fun agbatẹlẹ, bẹni, agbatẹlẹ ndi nkan si enia lọrun.

Ẹ jọwọ ẹnyin Alaşẹ ijọba Iwọ Orun ti aşẹ mbẹ lọwọ rẹ loni, o yẹ ki ẹ ba awọn bawọnyi sọrọ.

Emi ko pa lasẹ o, şugbọn mo fi siwaju yin bi imọran

Bere Oju iwe 8



OLOYE ỌLATUNJI, ỌGBONI ILẸŞA

On ni alaga kotu Ile ti Ilesa. Akọle Oloto sọrọ nipa kotu na wipe bi wọn tişe ma nşe ẹjọ nibe bu Ijẹsa ku nitoripe ero iworan ma nda si ọrọ kotu ibẹ. Akọle na daba pe o yẹ ki awọn adajọ to mọwe ma şe iranlọwọ fun kotu na.

## IDAHUN ỌRỌ S.A FAŞUPINRẸ

Lati ọwọ R.A.Awe Tailor Serikin Powa

Ẹniti olẹ Ileşa do ni o ba Baba yi ninu oko ila ti o nro inu rẹ on ni awọn enia fi npe Baba ni "Baba onila" titi.

Nigbti awọn enia npọ si tiwọn jẹ Ọba fun ra wọn, ninwọn wa fi Baba Onila jẹ igba keji ọba.

Anfani Baba Onila yi nigbati Qw jẹ ovẹ yi' ni awọn enia kuku npe ni "Obala" titi di oni yi.

Ki işe pe o dun leti enia tabi wọn kan ẹ sọ ni o. Eyiti mọmọ niyio.

Olotu, mo dupẹ nye ti e gba mi yi o, iwaju lọ-pa ẹbiti re si o



ẸGBẸ AWỌN ỌMỌ IJẸŞA NI EKO NI 1949 SI 1950

Awọn to joko lati apa ọtun ni awọn Ọgbẹni D. Olu Oladẹru, S. I. George, T. A. Ọlọjẹ, J. A. Lawrence, S. Ọbakayọde Ẹsọ, S. I. Jacobs, M. B. Ilesanmi, Adetumi Haastrup, S. L. Benson. Awọn to wa ni arin lati apa ọtun ni awọn Ọgbẹni S. Akindele Ojo, Timothy Haastrup, Alex O. Aafolaju-wọnlọ, A. Obe, E. A. Kupoluyi (to di ologbe), Ade. Ariyọ, E. A. Adeyẹye, Sanni A. Karimu, George Ademokoya, Ogunjuyagbe. Awọn to wa lẹhin lati apa ọtun ni E. B. Fajuyitan, Adenitan Ataiyerọ, D. Ọşundahusi, M. O. Ajayi, Josiah Akinyẹye, J. A. Idowu, M. B. Lajubutu, Ojo Ademuyiwa ati Adejuwọn Ọgial.

# IROHIN LATI AGBEGBE

## ORITA IDOMINASI NFẸ ISỌ ỌJA ?

(Lati Ọwọ S. O. Ajumọbi, Idominasi)

Olotu, inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye ninu iwe Irawọ Obokun, lati sọrọ diẹ lori isọ ọja orita Idominasi.

Lati igba lai lai wa ni ẹnyin ọkawe mi yio ripe ọja ojojumọ pẹlu awọn enia ti nṣowo koko ti wa ni orita Idominasi, ṣugbọn rogbodiyan ti o ṣelẹ ni Idominasi ni ọdun diẹ sẹhin lo mu ki ifasẹhin pe

Lẹhin igbati rogbodiyan yi kaṣe tan ni awọn enia wun bẹrẹ si ọja na lati mu na gẹgẹbi ti atijọ. Nisisiyi nkọ, ero ti awọn ara ilu Idominasi ati awọn ero lati Ilẹṣa, Ọṣogbo ati awọn ilu miran gbogbo nju lori igbega ọja na ki ṣe kekere nitoripe ọpọlọpọ lo fẹ kọ ile ipamọ (store) sibẹ, ọpọlọpọ enia lo si ti mura tan lati ṣi ile-itaja (shop) sibẹ pẹlu.

Lasiko yi, ọpọlọpọ ni ọja ti awọn nta ti nwọn si nra nibẹ, orişirişi onje ati mimu lo si wa nibẹ pẹlu fun awọn ero.

Ẹnyin ọmọ Obokun, ko si igbakugba ti ẹ ba de orita Idominasi yi ti ẹ ko ni ba ogunlọgọ enia nibẹ, papa julọ awọn ti o le wọ ọkọ. Ohun ti o jẹ ẹdun ọkan mi nipe ki ṣe kekere iya lo nje awọn enia nibẹ lakoko ojo ati lakoko ẹrun nitoripe buka ti o wa nibẹ ko to nkan.

Nitorina mo bẹ ẹnyin I g b i m ọ Ijọba Ọṣun, papa julọ ẹnyin ẹlẹgbẹ mi (N. C. N. C.) ti ẹ wa nibẹ, ki ẹ ba mi bojuto ọrọ yi lati ri wipe ẹ fi ile ọja yi (Market stalls) da Idominasi lọla nitoripe ohun ti o ba ndunni, on ni a nsare lọ mu loju ogun,

---

IJẸBU-JẸSA

## LORIỌMO ODO-ẸṢẸ FẸ GBIBỌDE

(Lati ọwọ Kansẹlọ J. B. Awẹ, Ijẹbu-Jẹṣa)

Ninu oṣu ti o kọja ni Igbimọ ti o nṣe eto owo ori ni ilu Ijẹbu-Jẹṣa kowe si gbogbo awọn Loriọmọ merẹrin ti ilu Ijẹbu-Jẹṣa ati awọn ilu ti o wa ninu igbimọ Ijẹbu-Jẹṣa wipe owo ori sisan yio bẹrẹ ninu oṣu ti a wa yi ati pe ki awọn Loriọmọ wọnyi ma lo agogo ni ọjọjọ Sande titi di akoko ti a o bẹrẹ si owo ori yi sisan ki o ma ba ba ẹnikẹni ni ijafu. Gbogbo adugbo ati awọn ilu yoku gba si bẹ, ṣugbọn o ya ni lẹnu lati ri pe Loriọmọ Odo-Ẹṣẹ gba iwe yi ko fẹ lu agogo l'Odo-Ẹṣẹ mọ. Mo lero wipe kikọ ti o kọ lati lu agogo yi o repe on fẹ ti pa Ijọba Igbimọ Ijẹbu-Jẹṣa lara ni. Fun idi pataki pe Ọgbẹni Loriọmọ yi (Ajala) ti gba Ogboni Ijẹbu-Jẹṣa gẹgẹbi olọrun rẹ, ojojumọ l ma sfotibalẹ niwaju Ogboni Ijẹbu-Jẹṣa, ti o lo lọ gbelẹ loko Ogboni ni Oko-Eriru lowurọ lowurọ.

Bọya olọrun rẹ yi lo sọfun pe ki o maṣe lu agogo, nikan ko le sọ, ṣugbọn ohun kan ti o gba irenu si nibẹ nipe Ọgbẹni Loriọmọ yi nikan ni o jẹ iriju Ogboni ninu gbogbo awọn yoku, on nikan na ni o nṣe lebira ninu oko Ogboni, on nikan yi lo kọ lati lu agogo.

Mo wa funra si wipe "Bi ina ko ba lawo lẹhin ki jo de odi keji omi. O dun ni diẹ wipe Ọgbẹni Ajala yi ti gbagbe ifẹ ti awọn ọmọ adugbo yi ni ninu on ki nwọn to fi on jẹ Loriọmọ. O jẹ tan ko wulo fun awọn ọmọ Odo-Ẹṣẹ mọ, o wa sọ ara rẹ di Lorimọdedo afin ati Lorimọdedo Ogboni.

Mo wa ng ba gbogbo awọn ọmọ Ijẹbu-Jẹṣa olyanju papa awọn ara Odo Ẹṣẹ wipe ki nwọn maṣe gbiyanju lati tapa si ofin. Nitoripe ẹniti ko ba san owo ori rẹ lasiko a o pe lọjọ si ile idajọ. Ogboni Ijẹbu ni yio dajọ rẹ, iba ṣe pe nwọn jẹ ọmọ iya.

Nitorina ẹ maṣe gbiyanju lati da ara yin loro. "Nitoripe Obokun mọ ẹniti nsin on".

---

## ILU ẸSA—ODO NFẸ ABOJUTO

Mo dupẹ lọwọ Olotu irawọ Obokun fun aye ti e gba mi lati sọ diẹ ninu nkan ti o nṣẹlẹ ni ilu Ẹsa-Odo latẹhinwa titi di oni yi.

Ni ọjọ 26 : 9 : 55, ni mo mura lati lọ si Ijẹbu-Jẹṣa ni ẹẹrẹ ti mo jade ni Ile-iwe, kini mo ri ? Bẹni mo wa ri awọn ara ilu mi loju ọna pẹlu ẹnikan ti ẹjẹ wẹ kanlẹ ẹrẹ bami pe ki lo de ? Nigbati wọn si gbe ẹnu le ọrọ yi mo wa ripe ẹniti wọn ṣa lọgbẹ yi kosi ọna ti o fi yẹ ki wọn ṣa lọ gbẹ rara, nitoripe ko mọ ọwọ ko mọ ẹsẹ wiwa awọn ti o ṣa lọgbẹ wa si ile rẹ.

Kilo tun jẹki o dun mi ti o si ya mi lẹnu ? On nipe lẹhin ti wọn ti ṣa lada tan ni wọn tun bẹrẹ si ja ti nwọn tun ba ọpọ nkan jẹ nile ẹniti wọn ṣa lada yi.

Njẹ ti alabojuto kan hawa nibẹ (Akọda), njẹ iru ija bẹ le sile ? Nitori idi eyi ki ijọba Ijẹṣa bi wa gba ọrọ yi yẹwo ki a na N. A. Akọda kan ni ilu Ẹsa-Odo.

---

## IRAWO OBOKUN FUN ERINMO

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lati ra Irawọ Obokun ni Ẹrinmọ ati agbegbe rẹ ki o bere lọdọ Ọgbẹni Samuel O. Ogundele, Ọna Ẹfọn No 644 Ẹrinmọ.

---

FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.



ỌGBẸNI LAWRENCE AMOKEODO

On jẹ ọkan ninu awọn aṣaju ẹgbẹ Carpenter ti Ilọ Ijẹṣa. Gbogbo ẹgbẹ Carpenter lati Ode Agbaiye nran aṣoju bọ ni ipade kan ti wọn yio ṣe lati ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu yi si ọjọ kọkanlelọgbọn.

---

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

| | | | |
|---|---|---|---|
| | OJU EWE KINI | | |
| Igba | 1—12 | 8s. | fun insi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |
| | OJU EWE KEJI | | |
| Igba | 1—12 | 5s | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |
| | OJU EWE KẸTA | | |
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |
| | OJU EWE KẸJỌ | | |
| Igba | 1—12 | 6s. | fun insi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE [illegible]

